# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KẸ́SÀN, ỌDÚN 2023**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**ÀDÚRÀ SÓRÍ OHUN-ÈLÒ IṢẸ́ (2)**

**OṢU KẸSAN 2023 – ADURA SORI OHUN ELO IṢẸ (2)**

**AWỌN ORIN IBẸẸRẸ**

1. **Ọkàn mi sọ, títóbi Olúwa!**

Àìlóye ibùkún lát'ọ́dọ̀ Rẹ;
Ìlérí ọ̀rọ̀ Rẹ kún fún tùnú;
Nín'Olùgbàlà l'ọkàn mi yó yọ̀.

2. Ọkàn mi sọ, títóbi Olúwa!

F'iṣẹ́ Rẹ hàn àt'ohun t'Ó tí ṣe;
Ànú Rẹ́ wà láti ìrandíran;
Orúkọ mímọ́ Rẹ̀ sì lágbára.

3. Ọkàn mi sọ, títóbi Olúwa!

Ìtẹ́ àti Ìjọba tẹríba;
Ọkàn tó gbéràga, a rẹ̀ sílẹ̀;
Ó gb'ónírẹ́lẹ̀ at'álàìní ga.

4. Ọkàn mí sọ ti ògo Ọ̀rọ̀ Rẹ̀!

Ìlérí Rẹ̀ àt'ánú Rẹ̀ dájú;
Ọkàn mí sọ títóbi Olúwa;
Fún'ran tó mbọ̀ àti títí ayé.

1. **Ọm'ogun Kríst', dìde,**

Mú 'hámọ́ra nyín wọ̀,
Lọ̀'pá t'Ọ́lọ́run fi fún nyin
Nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀:
Gbé'pá Ọlọ́run wọ̀,

T’Ólúwa ọm-ogun;
Ẹnit’ ó gbẹ́kẹ̀lé Jésù
Ó ju aṣẹ́gun lọ.

2. Nínú ipá Rẹ̀ nlá,
Ni kí ẹ sá dúró;
Mú ‘hámọ́ra Ọlọ́run wọ̀
Láti bá jìjà ná;
Lẹ́yìn ohun gbogbo
Lẹ́yìn ìjà gbogbo
K’ẹ lè ṣẹ́gun nípa Krístì,
K’ẹ sì dúró ṣinṣin

3. Ẹ kọjú s’ọ́tà nyín,
Pẹ̀lú ìjà kíkan;
Ogun Èṣù dojúkọ nyin
Lí ọjọ́ ibi nà
Kọlu ọmọ òkùn,
Ẹ f’ète wọn ṣẹ̀ṣín
Nínú ‘hámọ́ra Ìmọ́lẹ̀,
Àti ti òdodo.

4. Ẹ má f’àyè sílẹ̀
Fún àìlera ẹ̀mí;
F’ìwà-rere àt’or’ọ̀fẹ́
Mú ara nyín lókun:
Ẹ jùmọ̀ lọ s’ógun,
Láìsí ìyapa kan:

Ṣùgbọ́n ẹ fi ẹ̀mí Krístì
Ṣe ìhámọ́ra nyin.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo alábojútó ilé ìfowópamọ́ omi, tí wọ́n yàn ti ètò-ìṣúná mi, Olúwa bá ọ wí lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ibi gíga sátánì, tó n ró àwọn ọ̀tá mi lágbára, ìwọ yóò gba ìparun lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ìbápàdé àìmọ̀ pẹ̀lú ẹ̀mí ìpadàsẹ́yìn, kí agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù gba ẹ̀mí rẹ, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹ̀mí òògbé t'ẹ̀mí, àkokò rẹ ti dópin nínú ayé mi, jáde nípa iná báyìí, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn aba-ìyanu jẹ́ ní ilé bàbá mi, látònî lọ, ẹ kò tún ní ṣerere mọ́ nínú ayé mi, nítorínà, ẹ kú, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo iná àjèjì ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn lòdì sí ògo ayé mi, kú nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ahọ́n tí ó ní ìfòròróyán sátánì, tó n sọ̀rọ̀ ìkùnà sínú ayànmọ́ mi yóò gbẹ nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ**

### **ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ọwọ́ ibi tó n na ìka ẹ̀sùn lòdì sí mi, mo gé ọ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹnikẹ́ni tó wà lórí àga alàjá mi, ya wèrè, kosì kú, ní orúkọ Jésù.

5. Olúwa, jẹ́ kí àjálù dípò ayọ̀ ọ̀tá lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, jẹ́ kí ìbínú Rẹ tú ìpéjọpọ̀ àwọn ọ̀tá ká, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí orí ọ̀tá tó n yọmílẹ́nu rún wómúwómú, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Jòhánnù 14:27:** Àláfíà ni mo fi sílẹ̀ fún nyìn, àláfíà mi ni mo fifún nyín: kì ìṣe gẹ́gẹ́ bí ayé í ti fi fúnni li èmi fifún nyín. Ẹ máṣe jẹ́ kí ọkàn nyín dàrú, ẹ má sì jẹ́ kí ó wárìrí.

**2 Kọ́ríntì 2:14:** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹnití nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wa nígbàgbogbo nínú Krístì, tí Ó sì nfi orun ìmọ̀ Rẹ̀ hàn nípa wa níbigbogbo.

**1 Kọ́ríntì 15:55:** Ikú, oró rẹ dà: Iṣà òkú, ìṣẹ́gun rẹ dà?

**Jóṣúà 10:8:** Olúwa sì wí fún Jóṣúà pé, Má ṣe bẹ̀rù wọn: nítorítí mo ti fí wọ́n lé ọ lọ́wọ́; kì yóò sí ọkùnrin kan nínú wọn tí yóò lè dúró níwájú rẹ.

**Ìfihàn 12:11:** Nwọ́n sì sẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùtàn náà, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

**Hébérù 4:12:** Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yè, ó sì lí agbára, ó sì mú ju idàk'ídà olójú méjì lọ, ó sì n gúnni àní títí dé pípín ọkàn àti ẹ̀mí níyà, àti oríkè àti ọ̀rá inú egungun, òn sì ni olùmọ̀ èrò inú àti ète ọkàn.

**Fílíppì 4:13:** Èmi lè ṣe ohun gbogbo nínú Krístì ẹnití nfi agbára fún mi.

## ÌJẸ́WỌ̀ ÀTI ÀDÚRÀ SÓRÍ OHUN-ÈLÒ IṢẸ́

Bàbá, mo fi ohun-èlò làálà/iṣẹ́/òwò mi sí ọwọ́ mímọ́ Rẹ. Jẹ́ kí àwọn ohun-èlò wọ̀nyí kún fún ojúrere àtòkèwá, ònfà ìṣèrere, afa-àlàjá-mọ́ra, ìtayọ, agbára láti jẹ́ ẹni tí n winni, kì íṣe atọrọ, ìfàmì-òróró-yàn tó n yí ìtàn padà sí rere, àwọn àlàjá tíkòwọ́pọ̀, àti àgbègbè tó gbòòrò, ní orúkọ Jésù.  Mo ri ohun-èlò làálà/iṣẹ́/òwò mi sínú ẹ̀jẹ̀ Jésù àti iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.

1. Mo fọ́ ègún òṣì nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ẹ̀mí tó n mu ẹ̀jẹ̀ ọrọ̀ mi, mo gbé ọ dè, ní orúkọ Jésù.
3. Mo bá gbogbo ajẹnirun nínú ètò-ìṣúná mi wí, ní orúkọ Jésù.
4. Mo túká agbárakágbára tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìmúnádóko mi, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí ọrọ̀ àwọn kefèrí gba ìṣípò-padà sọ́dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, darí mi lọ sọ́dọ̀ àwọn tí yóò bùkún fún mi, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí a gbin ònfà ìṣerere àtòkèwá sínú àwọn ọwọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
8. Èmi yóò dìde ga ju àwọn aláígbàgbọ́ tí ó yímiká lọ, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, ṣe mí ní ìtọ́kasí àpẹẹrẹ rere fún àwọn ibùkún àtòkèwá, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí ìfòróróyàn ìtayọ bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, somípọ̀mọ́ àwọn olùrànlọ́wọ́ àtòkèwá, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo àwọn tó kórira ìṣerere mi gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
13. Èmi kòní kú láìṣepé adámimọ̀, ní orúkọ Jésù.
14. Èmi kòní kú láìní ìwúlò àti láìjẹ́pé a kókìkí mi sí rere, ní orúkọ Jésù.
15. Èmi kòní kú láìso èso àti láìní ìmúṣẹ, ní orúkọ Jésù.

16. Èmi kòní ju ọwọ́ sílẹ̀ nítorí mo gbàgbọ́ láti rí ire Olúwa ní ilẹ̀ alàààyè, ní orúkọ Jésù.
17. Afẹ́fẹ́ àṣetì kòní fẹ sí ìhá ọ̀dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
18. Mo gba okun Olúwa láti fo odi kòṣééṣe, ní orúkọ Jésù.
19. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo gba àwọn ìyanu tí yóò ya àwọn ọrẹ́ mi lẹ́nu, tí yóò sì já àwọn ọ̀tá mi láyà, ní orúkọ Jésù.
20. Nípa agbára tó pín Òkun Pupa sí méjì, Olúwa, jẹ́ kí ọ̀nà mí là, ní orúkọ Jésù.
21. Nípa agbára tó pín Odò Jọ́dánì sí méjì, Olúwa, jẹ́ kí àlàjá mi tíkòwọ́pọ̀ farahàn, ní orúkọ Jésù.
22. Ọlọ́run Èlíjàh, dìde, kí O sì sọmí di àrà merìrí àdìtú, ní orúkọ Jésù.
23. Nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tíkò ṣe é fọ́, mo wọnú ìpele mi tókàn lọ, ní orúkọ Jésù.
24. Àkokò ẹ̀rín mi tíkòwọ́pọ̀ àti ijó ìṣẹ́gun, farahàn, ní orúkọ Jésù.
25. Olúwa, tún àyíká mi tò láti mú ojúrere bá mi, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti tú àwọn àlùmọ́nì mi ká, gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
27. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti tẹrí ìgbésókè mi ba, kú, ní orúkọ Jésù.
28. Ọ̀pá ìkà tó n gbógun ti ìtẹ̀síwájú mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.